# Ìtúpalẹ̀ Ewì Aláwòrò-Ẹkùn Láàrin Àwọn Àwórì

Rifqat Ọ̀pẹ́yẹmí Sanni
Adeniran Ogunsanya College of Education,
Ọ̀tọ̀/Ìjànikin, Lagos
Nigeria
opesan03@yahoo.co.uk

## Àṣamọ̀

Onírúurú ọdún ìbílẹ̀ ló wà láàrin Yorùbá, ọ̀kan-ò-jọ̀kan ìbọ ni wọ́n sì máa ń fi sọrí àwọn ọdún ìbílẹ̀ wọ̀nyí. Ó fẹ́rẹ̀ẹ́ má sí ìlú kan láwùjọ Yorùbá tí kò ní ọdún ìbílẹ̀ kan tí wọ́n ń ṣe ní pàtó. Ọ̀rọ̀ nípa ìbọ àti ọdún ìbílẹ̀ kì í ṣe àjòjì ní ìpínlẹ̀ Èkó, ní pàtàkì jù lọ láàrin àwọn Àwórì. Onírúurú iṣẹ́ akadá ni ó ti wà nílẹ̀ lórí ewì alohùn inú àwọn ọdún ìbílẹ̀ àti ìbọ ilẹ̀ Yorùba ṣùgbọ́n kò sí èyíkéyìí nínú àwọn tí a ka tí ó gbájú mọ́ ìbọbìnrin láàrin àwọn Àwórì ní ìpínlẹ̀ Èkó tàbí ewì inú ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn tí iṣẹ́ yìí dá lé. Èyí mú kí á lè sọ pé, kò tí ì sí ìtúpalẹ̀ ewì ìbọbìnrin láàrin àwọn Àwórì ní ìpínlẹ̀ Èkó tí a rí.

Èròǹgbà wa nínú iṣẹ́ yìí ni láti ṣe ìtúpalẹ̀ ewì àti iṣẹ́-ọnà inú ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn láàrin àwọn Àwórì ní ìpínlẹ̀ Èkó. A kò fi òdiwọn sí ewì alohun tí a múlò, a ṣe àgbàsílẹ̀ gbogbo èyí tí a bá pàdé nínú bíbọ Aláwòrò-Ẹkùn. A sì tún ṣe ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò fún abọrẹ̀ Aláwòrò-Ẹkùn àti àwọn olùsìn mẹ́ta. A ṣe ìtúpalẹ̀ àbọ̀ ìwádìí pẹ̀lú tíọ́rì ìfiwádìí-sọ̀tumọ̀ àti tíọ́rì jẹ́ńdà. Èyí jẹ́ kí a ní òye pé, takọ-tabo ló ni ipa tí wọ́n ń kó nínú ọdún àti bíbọ ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn, bẹ́ẹ̀ ni a rí ihà tí obìnrin kọ sí ọkùnrin, ìhà tí ọkùnrin kọ sí obìnrin, àti ìhà tí àwọn obìnrin kọ sí ara wọn ní ojúbọ. Ohun gbogbo tí a tọ́ka sí nípa ewì alohùn Aláwòrò-Ẹkùn àti ìlò ohun èlò pọ̀ mọ́ ewì alohùn wọ̀nyí jẹ́ kí a lè sọ pé ipa pàtàkì ni àwọn ewì alohùn ń kó nínú bíbọ ìbọ àti ọdún láwùjọ Yorùbá, àti ní pàtàkì jùlọ nínú ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn láàrin àwọn Àwórì ní ìpínlẹ̀ Èkó.

## Ìfáàrà

Ọ̀rọ̀ nípa ìbọ àti ọdún ìbílẹ̀ kì í ṣe àjòjì ní ìpínlẹ̀ Èkó, ní pàtàkì jù lọ láàrin àwọn Àwórì. Gbogbo ẹ̀yà tó wà ní ìpínlẹ̀ Èkó ló ní ìbọ àti ọdún ìbílẹ̀ tí wọ́n ń ṣe láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ẹ̀sìn àjòjì tí mu kí àwọn kan má kọbi ara sí nínú àwọn ìbọ yìí bí ti àtẹ̀yìnwá, síbẹ̀ a ṣì rí àwọn ìbọ tí àwọn olùsìn wọn àti

ará ìlú kà sí dandan. Lára àwọn ọdún ìbílẹ̀ àti ìbọ tí ó jẹ́ gbajúgbajà, tí ẹ̀sìn àjòjì kò ráàyè parẹ́ ní ìpínlẹ̀ Èkó ni Ẹ̀yọ̀, Aasà, Agẹmọ, Ẹ̀lúkú, Ẹ̀rìbì, Orò, Sàńgbétọ́, Kílájolú, Egúngún, Àgbó-rémirékè, Ẹ̀rìbì, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Bí Yorùbá ti ní ọdún ìbílẹ̀ tó wà fún bíbọ àwọn òrìṣà kan, ni Yorùbá ní ọdún tó wà fún ayẹyẹ oríkádún, bẹ́ẹ̀ àwọn ọdún ìbílẹ̀ tí wọ́n fi béèrè fún nǹkan bí i ọmọ, àlàáfíà tàbí ohun mìíràn kò gbẹ́yìn. Ipò pàtàkì ti ewì alohùn wà láàrin àwọn Yorùbá ló tọ́ka iṣẹ́ pàtàkì tí wọ́n fi ń ṣe nínú ètùtù àti bíbọ àwọn ìbọ, yálà ìbọkùnrin tàbí ìbọbìnrin. Níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́ pé láti lè béèrè fún ohun tí a ṣe àìnì rẹ̀, kí a dúpẹ́ èyí tí a rí gbà, kí á sì béèrè tàbí fi èrò ọkàn wa ráń ìbọ̀ sí Elédùà ló mú wà dé ìdí ìbọ, ó dájú pé iṣẹ́-ọnà ajẹmóhùn-ẹnu ṣe pàtàkì ní ojúbọ. Ìwúlò Iṣẹ́-ọnà ajẹmóhùn-ẹnu lásìkò ìbọ tàbí ọdún kò ṣe é fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn, ipa pàtàkì ni wọn sì ń kó lórí ìbọ àti àwọn olùsìn.

## Èròǹgbà Iṣẹ́ Ìwádìí Yìí

Gẹ́gẹ́ bí ìwádìí ti fi hàn, onírúurú iṣẹ́ akadá ni ó ti wà nílẹ̀ lórí lítíréṣọ̀ alohùn inú àwọn ọdún ìbílẹ̀ àti ìbọ ilẹ̀ Yorùba. Ṣùgbọ́n a kò rí èyíkéyìí nínú àwọn tí a kà tí ó ṣiṣẹ́ tí ó gbájú mọ́ àwọn ìbọbìnrin láàrin àwọn Àwórì ní ìpínlẹ̀ Èkó tàbí ewì inú àwọn ìbọ wọ̀nyí. Èyí mú kí á lè sọ pé, wọn kò tí i ṣe ìtúpalẹ̀ ewì alohùn ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn láàrin àwọn Àwórì ní ìpínlẹ̀ Èkó. Nítorí náà, bí a bá ṣe ìwádìí lé e lórí kò léèwọ̀. Èròǹgbà wa nínú iṣẹ́ yìí ni láti ṣe ìtúpalẹ̀ ewì Aláwòrò-Ẹkùn láàrin àwọn ẹ̀yà Àwórì ní ìpínlẹ̀ Èkó. Ní pàtàkì, a ṣe àgbéyẹ̀wò ìlò ewì nínú bíbọ ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn àti ìtọ́kasí ipò àti ipa takọ-tabo nínú ìbọbìnrin yìí.

## Ọgbọ́n Ìṣèwádìí

Iṣẹ́ yìí ṣe àmúlò ìlànà méjì láti ṣèwádìí. Ṣíṣe àwárí àwọn ìbọbìnrin tí ó wà láàrin àwọn Àwórì ní ìpínlẹ̀ Èkó ni ìgbésẹ̀ àkọ́kọ́ tí a gbé. Èyí jẹ́ kí a lè yan ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn (Abo) ní ìlú Arárọ̀mí-Ale ni agbègbè Bàdágìrì. Bákàn náà a ṣe ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu wò fún Abọrẹ̀ (Ọ̀ṣùkù-Alále) Aláwòrò-Ẹkùn àti olùsìn ìbọ mẹ́ta. Olùwádìí kópa ní ojúbọ ìbọ, èyí fún un ní àǹfààní láti ya àwòrán oríṣìíríṣìí iṣẹ́-ọnà. A sì ká gbogbo ètò ìbọ àti gbogbo ewì alohùn tí wọ́n mú lò ní ójúbọ sílẹ̀ ní àkókò ìbọ.

## Tíọ́rì Ìfìwádìí-sọ̀tunmọ̀

Àwọn onímọ̀ fi múlẹ̀ pé, ara tíọ́rì ìfojú-inú-wo-ẹ̀mí-iṣẹ́ ni ìfiwádìí-sọ̀tunmọ̀ ti sun jáde. Aristotle ló ṣẹ̀dá tíọ́rì yìí ní nǹkan bí ọdún 360BC sẹ́yìn fún ìtúpalẹ̀ àwọn afọ̀ ajẹmọ́-ẹ̀sìn nígbà náà. Eagleton (1983:66) ṣàlàyé pé, nígbà tí ó di ọ̀rùndún kọkandínlógún (19th Century), àwọn onímọ̀ tíọ́rì yìí bẹ̀rẹ̀ sí ní lò ó fún ìtúpalẹ̀ àwọn afọ̀ mìíràn tí ó yàtọ̀ sí ti ẹ̀sìn. Edmund Husserl (1964) ni ó dá tíọ́rì náà sílẹ̀ fún ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ ajẹmẹ́sìn. Ní ọ̀rúndún kọkàndínlógún (19th

Century) ni wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí ní lo tíọ́rì ìfìwádìí-sọ̀tumọ̀ fún iṣẹ́ lámèétọ́ nínú lítíréṣọ̀ yàtọ̀ sí ìwé tí ó jẹ mọ́ ẹ̀sìn àti ọ̀rọ̀ ẹ̀sìn.

Ìṣèwádìí nípa ìtumọ̀ iṣẹ́-ọnà ni tíọ́rì yìí gbájúmọ́ ní tòótọ́. Àwọn àgbátẹ̀rù tíọ́rì yìí sì pọ̀ níye, lára wọn ni a ti rí Martins Heidegger (1962), Edmund Husserl (1964), Hans-Georg Gadamer (1976 & 1977), Wolfgang Iser (1980), Eagleton (1983), Davy (1999) àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Àwọn agbátẹ̀rù tíọ́rì yìí bí i Eagleton (1983), Davy (1999) àti àwọn mìíràn bẹ́ẹ̀ ló fẹ̀ tíọ́rì yìí lójú láti rí sí abala àwọn èdè tó ta kókó nínú afọ̀. Wọ́n gbà pé bí lámèétọ́ kò bá gbọ́fá èdè inú afọ̀ kan yéké yéké, yóò nira fún un láti fún afọ̀ bẹ́ẹ̀ ní ìtumọ̀. Ìdí tí wọ́n fi gbà bẹ́ẹ̀ ni pé, èdè tí aṣafọ̀ bá ṣe àmúlò nínú afọ̀ lè ṣókùnkùn sí lámèétọ́ bí kò bá mọ̀ nípà èdè náà. Nítorí náà, kò yẹ kí lámèétọ́ ta kété sí aṣafọ̀ bí ó bá fẹ́ ṣe ìtúpalẹ̀ tó lọ́ọ̀rìn nípa afọ̀ kan. Ohun tí ó ṣe pàtàkì ni pé, lámèétọ́ gbọ́dọ̀ ṣe ìwádìí tó jinlẹ̀ nípa títúmọ̀ afọ̀ tí aṣafọ̀ kan bá gbé kalẹ̀. Bẹ́ẹ̀ ni ó hàn nínú àlàkalẹ̀ wọn pé, a kò lè rí ìtumọ̀ kíkún nípa iṣẹ́-ọnà kan bí a bá fi ojú tàbí òté kan ṣoṣo wò ó. A yàn láti lo tíọ́rì yìí nítorí ìwádìí kíkún nípa ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn, ohun èlò ìbọ, ewì alohùn àti èdè tí àwọn olùsìn lò ní àkókò ìbọ ni yóò mú kí iṣẹ́ yìí kẹ́sẹ járí.

## Tíọ́rì Jẹ́ńdà

Ìtàn ìdìde jẹ́ńdà ni oríṣìíríṣìí ojú ìwòye nípa takọ-tabo. Abala ẹ̀kọ́ yìí ṣe àyẹ̀wò àwọn ọ̀na tí ìtàn, àṣà, àti àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ gbà nípa lórí takọ-tabo ní oríṣìíríṣìí àwùjọ. Ìmọ̀ yìí bẹ̀rẹ̀ nípasẹ̀ ìdìbó fún ìjìjàǹgbara àgbáyé ní èyí tó wáyé ní ọ̀rùndún ogún (20 Century). Ìgbésẹ̀ ìjìjàǹgbara àwọn obìnrin ní àárín ọdún 1960 sí 1970 mú kí àwọn aṣègbèfábo ṣe àtúnṣe sí ìtàn àjùmọ̀gbà tí wọ́n mọ̀ nígbà nípasẹ̀ ṣíṣe ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò oníwádìí-fín-ìdí-kókò. Èrò àwọn aṣègbèfábo ní àkókò yìí ni láti ṣe ìwádìí lórí èrò àwùjọ nípa ọkùnrin àti obìnrin, mọ ohun tí wọ́n jẹ́ gàn-an, kí wọn sì jábọ̀ ìyàtọ̀ tí wọ́n kíyèsí nípa obìnrin àti ọkùnrin (Chafetz,1999).

Ìmọ̀ jẹ́ńdà wáyé láti ara ìmọ̀-ìjìnlẹ̀ àti lítíréṣọ̀, ó sì ní í ṣe pẹ̀lú onírúurú ìmọ̀ ẹ̀kọ́ tí ó ń ṣe ìtúpalẹ̀ ìdánimọ̀ lákọ-lábo, aṣojú lákọ-lábo, ọ̀rọ̀ obìnrin, lákọ-lábo àti ọ̀rọ̀ ìṣèlú, ẹ̀kọ́ nípa àwọn ọkùnrin àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ìtàn ìdìde ìmọ̀ nípa jẹ́ńdà ṣe àgbéyẹ̀wò oríṣìíríṣìí abala nípa lákọ-lábo. Ó ṣe àyẹ̀wò sí ọ̀nà tí ìtàn ìwaṣẹ̀, àṣà àtí ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ ṣe tún ojúṣe lákọ-lábo rọ̀ ní àwọn àwùjọ wa. Ọ̀nà láti ṣiṣẹ́ tó yànjú mú kí ẹ̀kọ́ nípa jẹ́ńdà gbájúmọ́ ìyàtọ̀ tó wà láàrin ọkùnrin àti obìnrin, ìyàtọ̀ ìbálòpọ̀ àti ojúṣe kálukú. Tíọ́rì Jẹ́ńdà jẹ́ ẹ̀kọ́ nípa ohun tí a mọ̀ sí lákọ-lábo ní àwùjọ kan, ìlú kan tàbí nínú àwọn nǹkan bí i lítíréṣọ̀, ìtàn ìwáṣẹ̀, ẹ̀kọ́ nípa ìbára-ẹni-gbépọ̀, ẹ̀kọ́-ìwé, ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè, ẹ̀sìn, ìlera, ìmọ̀ ìjìnlẹ̀-èrò, àṣà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Jẹ́ńdà ni a lè tọka sí gẹ́gẹ́ bí i ìkọ́wọ̀ọ́rìn láàrin takọ-tabo nínú ìṣe. Simone de Beauvoir (1973: 37) ní, "one si not born, one is made a woman" (A kò bi

ọmọ lábo, a tọ́ ọ láti jẹ́ abo ni). Èyí fi hàn pé, àwùjọ ló yàn ojúṣe tí yóò tẹ obìnrin ba fún ọkùnrin fún wọn. Jẹ́ńdà ni ipa, ojúṣe, àrímọ̀ àti ìrètí tí àwùjọ gbé kalẹ̀ fún takọ-tabo tí wọ́n sì gbà pé ẹni tí a bá pè ní akọ tàbí abo gbọ́dọ̀ tẹ̀lé. Killermann (2017: 3) ṣiṣẹ́ lórí jẹ́ńdà ó ṣàlàyé pé, "Gender can also be broken into three categories, gender identity, gender expression and biological sex". (A lè pín Jẹ́ńdà sábẹ́ ìsọ̀rí mẹ́ta, ìyẹn àfihan tàbí ìjúwe lákọ-lábo, ìṣesí lákọ-lábo, àdámọ̀ lákọ-lábo). Àkíyèsí nípa èrò onímọ yìí ni pé, ohun mẹ́ta tí ó là kalẹ̀ wọ̀nyí lè ṣe àfihàn ìdámọ̀ lákọ-lábo láwùjọ.

Èrò àwọn onímọ̀ lórí jẹ́ńdà tí a mọ sí akọ àti abo kò fi gbogbo ara yàtọ̀ síra. Gbígbé ojúṣe wọ takọ-tabo, ìhà tí takọ-tabo kọ síra wọn láàyè kan, àjọṣepọ̀ takọ-tabo àti títo abo ati akọ pẹlú òṣùwọ̀n kan náà tí àwọn onímọ̀ yìí fi ìka tọ́ nínú àgbékalẹ̀ èrò wọn náà ni ó han ní ojúbọ Aláwòrò-Ẹkùn. Ọ̀kan-ò-jọ̀kan ipa, ipò àti ojúṣe akọ àti abo ní ojúbọ Aláwòrò-Ẹkùn ni a fi tíọ́rì yìí tú jádé, pẹ̀lú èrò láti lè sọ bóya akọ ní ipa tí wọn ń kó nínú ìbọbinrin tàbí abo nìkan lo ń kópa nínú ìbọbinrin.

Lílo tíọ́rì yìí yóò fún wà ní àǹfàní láti mọ nípa iṣẹ́ àti ìṣe tí àwọn olùsìn Aláwòrò-Ẹkùn yàn fún akọ lójúbọ ìbọbìnrin yàbọ sí ti obìnrin, bẹ́ẹ̀ ni yóò sì jẹ́ kí á mọ ipa tí àjọṣepọ̀ takọ-tabọ ń kó lórí ìbọ àti àwọn ìpohùn tó ń wáyé ní àkókò ìbọ. Àgbára tíọ́rì yìí kò débi wíwo èdè tí àwọn olùsìn fi gbé ewì alohùn kalẹ̀, kò ká wíwo àjọṣepọ̀ tó wà láàrin ohun èlò ìbọ àti ewì ìbọ, bẹ́ẹ̀ ni kò tú ìtumọ̀ tí àwọn ewì alohùn ní sí àwọn olùsin, ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn àti àwọn ẹ̀mí àìrí yòókù jáde. Èyí ló mú wa yàn tíọ́rì ìfiwádìí-sọ̀tunmọ̀ láti túṣu àwọn kókó tí a tọ́ka wọ̀nyí àti àwọn mìíran tí apá tíọ́rì jẹ́ńdà kò ká dé ìsàlẹ̀ ìkòkò.

## Àyẹ̀wò Iṣẹ́ Ìṣáájú Lórí Ìbọ Nílẹ̀ Yorùbá

Onírúurú èrò ní àwọn onímọ̀ ìṣáájú ti fi hàn lórí òrìṣà tàbí ìbọ láwùjọ Yorùbá ní pàtàkì jùlọ ní ìpínlẹ Èkó, èrò àti iṣẹ́ ìwádìí díẹ̀ nínú àwọn onímọ̀ wọ̀nyí ni a yẹ̀wò.

Ìdòwú-Ọ̀shọ́ (2005) ṣiṣẹ́ ìwádìí lórí ipa tí àwọn obìnrin ilé ń kó nínú ọdún Ẹ̀rùngbè (Ẹ̀lúkú) láàrin àwọn ìjẹ̀bú ìlú Ìkòròdú ní ìpínlẹ̀ Èkó. Ó fi hàn pé orin orò tí àwọn Ìjẹ̀bú ń pè ní Orin Ẹ̀rùngbè tàbí Ẹ̀lúkú ní ipa pàtàkì nínú ọdún tí wọn ń ṣe fún òrìṣà náà jákèjádò ilẹ̀ àwọn Ìjẹ̀bú ní ìpínlẹ̀ Èkó àti ìpínlẹ̀ Ògùn. Ó ṣàlàyé pé àwọn obìnrin kì í wọ igbó orò, ṣùgbọ́n ojúṣe wọn kò ṣe fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn nínú ọdún orò. Ewì alohùn tí ó jẹ yọ nínú ọdún Ẹ̀rùngbè ni onímọ̀ yìí múlò láti ṣàlàyé ipò pàtàkì tí àwọn obìnrin wà nínú àgbékalẹ̀ ọdún. Adéyẹrí (2012) gbà pé ipa tí ọdún ìbílẹ̀ ń kó nínú ìgbé-ayé àti ọrọ̀-ajé ìlú Ẹ̀pẹ́ kò kéré rárá. Ó ṣe àlàyé tó yanjú lórí àwọn ọdún Ọkọ̀ṣí, Àgbó, Agẹmọ, Èbì àti Káyó-káyó. Onímọ̀ yìí fi hàn pé ọ̀pọ̀ àwọn olùsìn ìbọ wọ̀nyí ń pa òfin ìbọ àti ọdún mọ nítorí ìgbàgbọ́ wọn pé èyí ló lè ran àlàáfíà, ìlọsíwájú àti ìlèra pípé àwùjọ.

Ó wakọ̀ iṣẹ́ yìí gúnlẹ̀ pé àwọn èrò tó máa ń wọ ìlú Ẹ̀pẹ́ ní àkókò ọdún ìbílẹ̀ ń lapa lóri ọrọ̀-ajé ìlú, ó sì ń mú ìgbéga àti ìdàgbàsókè bá ọrọ̀-ajé ìlú Ẹ̀pẹ́ lápapọ̀.

Loko (2014) ṣàlàyé pé ipa ribiribi ni orin ń kó nínú ọdún Egúngún Akẹ̀sán láàrin àwọn Àwórì. Ó gbà pé orin gan-an ni ọ̀pá tí a fi ń tukọ̀ ọdún Egúngùn ní Akẹ̀sán. Àkóónú àti koko-ọ̀rọ̀ inú orin ọdún yìí ni onímọ̀ yẹwò. Ó tọ́ka pé àwọn olùsìn Egúngún Akẹ̀sán àti àwọn akópa máa ń ṣe àmúlò orin lásìkò ọdún. Ó ṣàlàyé pé, ọ̀tọ̀ ni orin tó wà fún ètùtù, ọ̀tọ̀ ni orin ìwọ́de ọdún, bẹ́ẹ̀ ni orin ìpolongo, orin ìwẹ̀nùmọ́ yàtọ̀ sí ti ìdánilárayá. Ọ̀kan-ò-jọ̀kan ẹbí ìlù ní ó hàn pé wọ́n fi gbé orin lárugẹ ní àkókò ọdún Egúngún Akẹ̀sán. Ọbáṣọlá (2014) náà mẹ́nu bá oríṣìí Ẹ̀yọ̀ márùn-ún tó wà ní ìpílẹ̀ Èkó - Adimú, Ọ̀kọlàbà, Àgèrè, Ọlọ́gẹ̀dẹ̀ àti Oníko. Ó ṣàlàyé bí wọ́n ti ṣe ń ṣe ọdún ẹ̀yọ̀ àti bí ọdún yìí ṣe máa ń lárinrin tó. Ohun tó mumí láya onímọ̀ yìí ni àyẹ̀wò ẹ̀sìn, ìrìnàjò-afẹ́ àti ìdàgbàsókè. Ó tọka pé ọkan-ò-jọ̀kan ìṣòro tó wáyé nípasẹ̀ ẹ̀sìn bí i ìjà ẹ̀sin, ìdàrúdàpọ̀ ẹ̀sìn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ń ṣe àkóbá fún ìdàgbàsókè ọ̀rọ̀-ajé. Ó fi kun pé, ìrìnàjò-afẹ́ tó jẹ mọ́ ẹ̀sin bí ọdún Ẹ̀yọ̀ ni ànfààní gidi fún ìdàgbàsókè àwùjọ àti àwọn ẹ̀dá. Ó dábàá kí ìjọba ṣe ìgbéláruge fún ìrìnàjò-afẹ́ tó ní í ṣe pẹ̀lú ẹ̀sìn láti mú ìdàgbàsókè bá ọrọ̀-ajé.

Iṣẹ́ Agbábíàká (2016) tọ́ka pé Ẹ̀yọ̀ erékùṣù Èkó máa ń jáde ní àkókò ọdún ìbílẹ̀ pàtàkì ní ìpínlẹ̀ Èkó. Àwọn olùsìn kò gbé kalẹ̀ nítorí àti ṣe àyẹyẹ tàbí à-jọ̀dún, bí kò ṣe ní ìrántí àwọn akọni pàtàkì tó ti lọ. Ohun tí onímọ̀ yìí sọ wà ní ìbámu pẹ̀lú èrò Ọbáṣọlá (2014) nígbà tó tọ́ka pé ìsọ̀rí Ẹ̀yọ̀ márùn-ún ní ó wà ní ìpínlẹ̀ Èko - Adimu (Ẹ̀yọ̀ Òrìṣà), Ẹ̀yọ̀ Alákẹtẹ̀-pupa, Ẹ̀yọ̀ Oníko, Ẹ̀yọ̀ Ọlọ́gẹ̀dẹ̀ àti Ẹ̀yọ̀ Àgérè. Àgbéyẹ̀wò ipa òdì àfojúrí tí ìṣẹ àkókò ọdún Ẹ̀yọ̀ ń ní lórí àyíkà erékùṣù Èkó ni iṣẹ́ rẹ̀ dálé. Ó fi hàn pé ọdún Ẹ̀yọ̀ máa ń lárinrin ó sì máa ń fa wíwọ́ èrò bí i eṣú ní àwọn agbègbè tí ọdún yìí ti máa ń wáyé nítorí ó jẹ́ ọdún pàtàkì àti ọdún ayọ̀. Síbẹ̀ ó nípa òdì lórí àwọn olùgbé agbègbè ibi tí wọ́n ti ń ṣe ọdún. Lára ìpa tó fi heàn ni ọ̀pọ̀ súnkẹre-fàkẹrẹ ọkọ̀ lójú pópó, àpọ̀pọ̀jù èrò, ọ̀pọ̀ eruku àti òórun ìgbó, mímú kí ìwà-ọ̀daràn gòkè sí i, àpọ̀jù ariwo, mímú kí ọjà wọ́n gógó, àti dídọ̀ti àyíká. Onímọ̀ yìí kádìí iṣẹ́ rẹ̀ pẹ̀lú ìtọ́kasí ọ̀nà àbayọ́ pé kí àwọn agbátẹrù ọdún Ẹ̀yọ̀ máa ṣètò ààbò tó péye, àwọn olùṣọ́ ojúpópó, àwọn adarí ọkọ̀, àwọn kólẹ̀-kódọ̀tí àti ètò ìlana lọ́yẹ̀ ṣáájú àkókò tí ọdún yóò wáyé.

Àkíyèsí fi hàn pé, ọ̀kan-ò-jọ̀kan iṣẹ́ ni àwọn onímọ̀ ti ṣe lórí ìbọ àti ọdún ìbílẹ̀ àwùjọ Yorùbá àti ní pàtàkì jùlọ ìpínlẹ̀ Èkó. Bí àwọn iṣẹ́ yìí ti wá pọ̀ tó a kò rí èyí tó gbájúmọ wíwo ìbọbìnrin ní ìpínlẹ̀ Èkó, bẹ́ẹ̀ ni a kò rí onímọ̀ tó ṣẹ àyẹ̀wò ewì alohùn tó ń jẹ yọ nínú àwọn ìbọbìnrin ní ìpínlẹ̀ Èkó tàbí láàrin àwọn Àwórì àti ipa tí àwọn ewì wọ̀nyí ń kó nínú bíbọ ìbọ àti àwùjọ lápapọ̀. Àlàfo tí ó hàn yìí àti àwọn mìíran bẹ́ẹ̀ ni a yàn láti dí nínú iṣẹ́ yìí.

## Ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn ní Ìlú Arárọ̀mí-Ale

Aba Ìbíkúnlé Ajọsẹ̀ (Ọbá Arárọ̀mí-Ale àti Abọrè Aláwòrò-Ẹkùn) ṣàlàyé kíkún nínú ìfọ̀rọ̀wáni-lẹ́nu-wò pé nǹkan bíi sẹ́ńtúrì kẹrìndínlógún (16th Century) ni ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn akọ àti abo ṣe atọ́na Ìṣùkú-Alále, ìyẹn baba ńlá àwọn ìran Arárọ̀mí-Ale-koko-bí-ọta dé ìpínlẹ̀ Èkó láti Ilé-Ifẹ̀. Agboolé ọba Adéjùgbẹ̀ ní Ìtagbọn ní Ilé-Ifẹ̀ ni Ìṣùkú-Alále àti àwọn èèyàn rẹ̀ ti kúrò lọ sí Ọ̀yọ́-Ilé.[1] Wọ́n dúró sí Ọ̀yọ́-Ilé fún ìgbà díẹ̀, kí Ìṣùkú-Alále tó kúrò níbẹ̀ pẹ̀lú díẹ̀ nínú àwọn ẹmẹ̀wà rẹ̀ àti Aláwòrò akọ àti abo. Ó fi ìyàwó àti ọ̀pọ̀ nínú àwọn èèyàn rẹ̀ tókù sílẹ̀, láti lọ tẹ̀dó sí Arárọ̀mí-Ale tí wọ́n wà lónìí. Ọ̀pọ̀ ìlú ni wọ́n yà, tí wọ́n sì lo sáà díẹ̀ kí wọ́n tó dé Arárọ̀mí-Ale ní agbègbè Bàdágìrì ní ìpínlẹ̀ Èkó tí wọ́n wà lónìí. Lẹ́yìn ìgbà pípẹ́ tí wọ́n ti ń rìn, wọ́n dé ìlú Ọ̀jọ́ ní ìpínlẹ̀ Èkó. Ṣáájú àkókò tí wọ́n dé ìlú yìí oríṣìíríṣìí aburú ló ń wáyé láàrin àwọn èèyàn ibẹ̀ bí i Àjàkálẹ̀-àrun, ọlọ́ṣà, ìdigunjalè, ìfipámú-múni àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ìtàn fi yé wa pé, bí Ìṣùkú-Alále àti àwọn èèyàn rẹ̀ ṣe wọ ìlú Ọ̀jọ́ pẹ̀lú Aláwòrò méjèèjì yìí, gbogbo aburú tó ń ṣẹlẹ̀ nínú ìlú yìí dáwọ́ dúró, wọ́n sì bẹ̀rẹ̀ sí ní gbé ìgbé ìrọ̀rùn. Èyí ló ṣokùnnfà bí Aláwòrò-Ẹkùn ṣe di ìbọ tó ń gbé ní ìlú Ọ̀jọ́.


Aba Ibikunle Ajose tẹ̀síwájú pé nígbà tí ó ṣe, ìbọ Aláwòrò sọ fún Ìṣùkú-Alále pé, kò lè dúró níbi tí o wà yìí nítorí ibẹ̀ kì í ṣe ààyè rẹ̀. Èyí mú Ìṣùkú-Alále pinnu láti tẹ̀síwájú láti wá ààyè tí wọn yóò tẹ̀dó sí lọ. Wọ́n kúrò ní Ọ̀jọ́, wọ́n rìn títí tí dé ìlú Bàdágìrì. Aláwòrò-Ẹkùn sì dá wọn padà sẹ́yìn nítorí wọ́n ti kọjá ààyè ilẹ̀ tó jẹ́ ilẹ̀ wọ́n. Alagbalúgbú omi ni ààyè tí wọ́n wà lónìí yìí tẹ́lẹ̀ ṣùgbọ́n bí wọ́n ti dé ibẹ̀ ni ìbọ Aláwòrò ní ibi tí òun fẹ́ nìyí nítorí etí omi ni òun fẹ́. Wọ́n tẹ̀dó sí Arárọ̀mí Ale-koko-bí-ọta tí wọ́n wà lónìí.

Olóyè Samuel Ebenezer náà sọ àsọyán ọ̀rọ̀ pé, kò sí ìlú tàbí ẹ̀yà mìíràn tí ó ní Aláwòrò-Ẹkùn ju àwọn Àwórì Arárọ̀mí-Ale ní orílẹ̀ èdè Nàìjíríà. Abo Aláwòrò-Ẹkùn ní a yàn nínú iṣẹ́ yìí, kò jẹ́ ìyàlẹ̀nú pé ìrísí obìnrin ni a rí lára ère tí wọ́n fi rọ́pò ìbọ yìí. Àwọn olùsìn ìbọ gbà pé, ní gbogbo ìgbà tí àwọn bá ti ń wo tàbí dojú kọ ère yìí Aláwòrò-Ẹkùn gan-an ni àwọn dojú kọ.[2]

---

1 Ọbá ìlú Arárọ̀mí-Ale àti abọrẹ̀ Aláwòrò-Ẹkùn tí ó ṣàlàyé fún wa nípa bí ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn ṣe dé ìlú Arárọ̀mí-Ale ní agbègbè Bàdágìrì ní ìpínlẹ̀ Èkó. Ìgà Ọ̀ṣùkù-Alále ní Arárọ̀mí-Alé ni abẹ́nà-ìmọ̀ wa yìí ń gbé.

2 Oye Aṣẹ̀ ni alágbà yìí jẹ́ láàfin Ọ̀ṣùkù-Alále, ó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn abẹ́nà-ìmọ wa. Agboolé Ọ̀ṣùkù ní olóyè yìí ń gbé. Ó ṣàlàyé kíkún fún wa nípa bíbọ ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn àti àwọn ohun èlò ìbọ.



*Èré Osu, Ọ̀pá Bàbá àti Èré Aláwòrò-Ẹkùn*

Kíkópa nínú ètùtù bíbọ Aláwòrò-Ẹkùn jẹ́ kí a ní òye pé, kì í ṣe ère Aláwòrò-Ẹkùn nìkan ni ó wà ní ojúbọ rẹ̀. A rí Ọ̀pá bàbá àti ère Òsù ní ojúbọ yìí kan náà. Olóyè Samuel Ebenezer fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àwọn babanla àwọn gbé ere Òsù wọ̀lú pẹ̀lú Aláwòrò-Ẹkùn ni àti pé ère yìí kò ní nǹkan ṣe pẹ̀lú Èṣù. Bákan náà ni ó sọ ọ́ di mímọ̀ fún wa pé, ohun èlò tí àwọn n pè ní ọ̀pá Bàbá ní wọ́n ń pè ní Ọ̀pá Ọ̀rẹ̀rẹ̀ láàrin àwọn Ọlọ́bàtálá tàbí Ọ̀pá Ọ̀ṣun. Àwọn ọlọ́bàtálá a sì máa fi tẹlẹ̀ bí wọ́n bá múra awo tán tí wọ́n ń gbẹ́sẹ̀ awò ní ṣísẹ̀-n-tẹ̀lé tàbí tò lọ́wọ̀ọ̀wọ́ lọ sóde awo. Àmì pàtàkì ló jẹ́ ní ojúbọ Aláwòrò-Ẹkùn, èyí sì ń ṣe àfihan ìgbàgbọ́ àti àjọṣepọ̀ àwọn olùsìn Aláwòrò-Ẹkùn pẹ̀lú ìbọ Ọbàtálá. Akọ ni àwọn ìbọ wọ̀nyí ṣùgbọ́n wọ́n ní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú ìran Ìṣùkú-Alále tí ó ní Aláwòrò-Ẹkùn, èyí ló mú wọn kó ìbọ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta papọ̀ sí ojúbọ kan náà. Ọdún mẹ́ta-mẹ́ta ni wọ́n máa ń ṣe ọdún ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn, ọdún kókú lọ, kárùn lọ ni ọdún yìí máa ń jẹ́ ní ìlú Arárọ̀mí-Ale. Lára ohun èlò ìbọ yìí ni ẹmu-àjáàbalẹ̀, obì gbàǹja, obì àbàtà olójú mẹ́rin, aṣọ funfun àti adìyẹ ìbílẹ̀.



*Àwòrán 2: Ìmúra àwọn Olùsìn ní Àkókò Ìbọ*

Àwọn olùsìn Aláwòrò-Ẹkùn kọ́ ilé sí ààyè tí bàbá ńlá àwọn Arárọ̀mí-Ale gbé ère ìbọ yìí sí nígbà tí wọ́n kọ́kọ́ gbe wọ ìlú. Ààyè yìí náà sì ni Ààfin Ọ̀ṣùkù-Alále wà. Ilé ìbọ yìí ni àwọn olùsìn yà sọ́tọ̀ fún bíbọ àti ṣíṣe ayẹyẹ gbogbo nípa Aláwòrò-Ẹkùn.



*Àwòrán 3: Ilé Ojúbọ Aláwòrò-Ẹkùn (Abo)*

Ilé Ọwá ni àwọn olùsin ń pe ilé ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn. Wọ́n fi yé wa pé, ilé yìí dàbí ilé Ọ̀rànmíyàn ní Ilé-Ifẹ̀. Àmì pàtàkì ni ó sì jẹ́ fún àwọn olùsìn àti àwọn tí ó ní ìgbàgbọ́ nínú ìbọ yìí, ibi ọ̀wọ̀ ni ààyè yìí sì jẹ́.

## Ìpo àti Ipa Takọ-tabo nínú Ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn

Ó hàn dájú pé, ìbágbépọ̀-ẹ̀dá láwùjọ ló jẹ́ orísun ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn. Bí àpẹẹrẹ ọ̀rọ̀ lórí bí àwọn èèyàn ṣe ń ṣe àtìpó láti ìlú kan sí òmíràn pẹ̀lú èrò láti ṣiṣẹ́ ajé, wá ààyè tí yóò mú ìdẹ̀rùn bá ìgbésí ayé wọn àti láti sá àsálà kúrò lọ́wọ́ ogun tàbí aburú mìíràn farahàn nínú ìtàn tí ó ṣe Aláwòrò-Ẹkùn. Bẹ́ẹ̀ ló hàn pé akọ àti abo ni Aláwòrò-Ẹkùn tí wọ́n mu wọ ìlú Arárọ̀mí-Ale. Ojúṣe àti ipò pàtàkì wá fún àwọn ọkùnrin àti obìnrin nínú bíbọ ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn, èyí kò sì ṣe é fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn nínú àṣeyọrí bíbọ ìbọ.

Ọkùnrin ni Osuku, ìyẹn abọrẹ̀ Aláwòrò-Ẹkùn, òun ló ń darí gbogbo ètùtù àti ìwúre ní ojúbọ. Ó tún hàn pé àwọn ọkùnrin ló ń darí àwọn olùsìn obìnrin ní àkókò tí wọ́n wà ní ìforíbalẹ̀ láti júbà ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn. Ohùn ìsàrè ní àwọn olùsìn obìnrin yìí máa ń lò láti pe ìpọ̀nrí àwọn ẹ̀mí àìrí ìdí ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn wá sí ààrín wọn kí ohun gbogbo lè lọ lẹ́sẹẹsẹ.



*Àwòrán 4: Awọn Olùsìn Aláwòrò-Ẹkùn ní àkókò Ìjúbà*

Ó hàn pé, àwọn ọkùnrin ló ń lu ìlù àti agogo ní àkókò ìjúbà àti ayẹyẹ. Àwọn náà ló sì pín ohun-èlò ìrúbọ tí ó kù nílẹ̀ kárí gbogbo àwọn akópa tó wà ní ìjókòó ní àkókò ètùtù àti ayẹyẹ. Ìwádìí nípa ìbọ yìí fi hàn pé, obìnrin kò

lè jẹ Abọrẹ̀ ìbọ́ Aláwòrò-Ẹkùn, ìyálóde àti erelú ni wọ́n lè jẹ. Olóyè Samuel Ebenezer (Aṣẹ̀) tí ó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn abẹ́nà ìmọ̀ wa, fi yé wa pé bí ó bá wu olórí ìbọ, ó lè pé nínú àwọn olóyè obìnrin láti wúre fún àlejò tí ó bá wà ní ì-jókòó lákòókò ìbọ. Ìyálóde máa ń dúró ní ẹ̀gbẹ́ ọ̀tún Ọ̀ṣùkù ni àkókò tí ó bá ń ṣe ìwúre jẹ́jẹ́ ní ojúbọ kí ó tó da obì. Dídúró ìyálóde yìí kì í ṣe láti wúre tàbí dá sí ohun tí Ọ̀ṣùkù ń ṣe bí kò ṣe láti máa ṣe àṣẹ kí ó sì máa fi ọkàn bá ohun tí Ọ̀ṣùkù ń ṣe lọ, òun ní yóò sì kéde pé ìwúre kẹ́lẹ́kẹ́lẹ́ ti parí pẹ̀lú fífi ohun réré pàriwo "yéèpaaa!!!" ní ẹ̀ẹ̀mẹ́ta.

Yàtọ̀ sí èyí, bí oríṣìíríṣìí orin bá ti ń lọ ní àkókò ìbọ, ẹ̀mí àìrí tó wà ní ojúbọ yìí lè wọ̀le sára èyíkéyìí nínú àwọn olùfọkànsìn obìnrin tí ẹ̀gùn ìbọ yóò sì gùn onítọ̀hún. Àkókò ẹ̀gùn yìí ni ìbọ yóò lò láti ráńṣẹ́ sí àwọn olùsìn, ẹni tí ó wá bọ ọ́ tàbí ìlú lápapọ̀. Bí ara kò bá rọ olùsìn tí ó gẹ̀gùn lásìkò, lára àwọn olùsìn obìnrin yòókù ni yóò lọ sódò lọ pọn omi tí wọn yóò yán sí onítọ̀hún lára. Kíkópa nínú bíbọ Aláwòrò-Ẹkùn jẹ́ kí a rí i pé, ipa ribiribi àti ojúṣe pàtàkì wà fún àwọn obìnrin láti ara fífi tọkàn-tara ṣe ìsìn, ṣe ìtọ́jú, àpọ́nlé àti ẹ̀yẹ fún ìbọ, sìn ìbọ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Èyí kín èrò Johnson (1921) lórí jẹ́ńdà lẹ́yìn nígbà tí ó sọ pé, obìnrin ní aápọn iṣẹ́ ju ọkùnrin lọ, àti pé ìtọ́jú ilé kan obìnrin ju ọkùn-rin lọ lẹ́yìn.

Obìnrin àti ọkùnrin ló ń ṣe àṣẹ sí ìwúre, yálà ọkùnrin ló ń wúre ni tàbí obìn-rin. Bákan náà ní a rí ààyè tí ọkùnrin àti obìnrin tí jọ ń kọrin tí wọ́n sì ń jó ní àkókò àyẹyẹ. Ó hàn pé, aṣọ funfun kan náà ní àwọn olùsìn Aláwòrò-Ẹkùn ọkùnrin àti obìnrin ń wọ ní àkókò ìbọ. Bẹ́ẹ̀ ni a sì tún rí i bí takọ-tabo ṣe jìjọ sáre ìkasẹ̀ nígbà tí wọn parí ètùtù ní ojúbọ Aláwòrò-Ẹkùn.

Àwọn ojúṣe tí a tọ́ka wọ̀nyí àti àwọn mìíràn tó pa takọ-tabo pọ ni àwọn onítíọ́rì jẹ́ńdà fi múlẹ̀. Àwọn agbátẹrù tíọ́rì yìí gbà pé, lóòótọ́ ojú méjì ìyẹn akọ àti abo wà nínú ìhun àwùjọ, bẹ́ẹ̀ àwọn méjèèjì kò wà lásán, wọ́n ní àjọṣe àti ipa tí wọ́n ń kó lórí ara wọn àti ní ààyè tí a bá ti bá wọn pàdé. Fún ìdí èyí, a lè sọ pé, tíọ́rì jẹ́ńdà wúlò gidi fún títan iná wo àjọṣepọ̀ ọkùnrin àti obìnrin ní lojúbọ Aláwòrò-Ẹkùn, ipa àti ipò takọ-tabo ní ojúbọ, àyọrísí wo ló hàn nípasẹ̀ àjọṣepọ̀ takọ-tabo ojúbọ, ìhun ètò àti àṣà àwùjọ tó jẹ yọ ní ojúbọ Aláwòrò-Ẹkùn láàrin àwọn Àwórì ní ìpínlẹ̀ Èkó àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

## Ewì Alohùn inú Ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn

Àjọṣepọ̀ tí ó gbòòrò ni ó wà láàrin ewì alohùn àti ìbọ láwùjọ adúláwọ̀. Ìwádìí nípa ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn tilẹ̀ fi hàn pé iṣẹ́ tí ewì alohùn ń ṣe nínú bíbọ àwọn ìbọ tàbí òrìṣà kò kéré. Bákan náà ni ó hàn pé kò sí ìbọ tí kò ní ewì alo-hùn tí àwọn olùsìn ń múlò fún ìsìn àti ṣíṣe àyẹ́sí ìbọ. Bí àpẹẹrẹ oríkì ìbọ ni àwọn olùsìn fi máa ń pe ìpọ̀rí ìbọ kí ó lè wá sáàrin wọn ní àkókò ìbọ láti gbo-hun wọn tọ Elédùmarè, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n máa ń lo ohùn orin tàbí ìsàré láti júba àwọn ẹ̀mí tí àwọn olùsìn gbà pé ó wà ní ojúbọ. Bákan náà ni wọn ń lo ewì alohùn

láti wúre tàbí ṣépè. Wọ́n sì tún un lò o o láti dúpẹ oore ní ojúbọ pẹ̀lú ìlànà ìgbákalẹ tí àwọn olùsìn bá fara mọ́, yálà àrángbọ́, ìsàré tàbí ìsọ̀rọ̀-kéwì. Ewì alohùn ti ó jẹ yọ ní ojúbọ Aláwòrò-Ẹkùn ni a óò máa yẹ̀ wò báyìí.

## Ìwúre inú Ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn

Ọba Ìbíkúnlé Ajosẹ fi ìdí ọrọ̀ múlẹ̀ nínú ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò tí a ṣe pé, kò sí ibi ètùtù tàbí ìbọ tí ìwúre kò ti ń wáyé, ó fẹ́rẹ̀ jẹ́ ìwúre ni olúborí ní àkókò ìbọ ní ilẹ̀ Yorùbá. Ìlò ìwúre ní ojúbọ kò kére nítorí lọ́pọ̀ ìgbà, wíwá ọ̀kan, méjì tàbí gbogbo ire máràárún ló máa ń mú àwọn èèyàn lọ ṣe ètùtù tàbí bọ ìbọ tí wọ́n bá nígbàgbọ́ nínú rẹ̀. Èyí kò sì yàtọ̀ ní ojúbọ ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn.

Ó hàn pé, ojú ìwòyè Yorùbá nípa pé ìwúre máa ń lànà àṣeyọrí ẹ̀dá jẹ́ ohun pàtàkì lóókan àyà àwọn olùsìn àwọn Aláwòrò-Ẹkùn, èrò láti ṣe àṣeyè ló mú kí àwọn Yorùbá mú ìwúre ní kókó. Ìwúre jẹ́ ewì alohùn tí ó ti di máyẹ́ ní ojúbọ ilẹ̀ Yorùbá gbogbo, ní pàtàkì láàrin àwọn ìbọbìnrin. Ìwádìí fi hàn pé, àwọn olùsìn Aláwòrò-Ẹkùn mú ìwúre ni kókó, wọ́n kanlẹ̀ máa ń ṣètò bíbọ ìbọ àti ètùtù torí àti bèèrè ohun tí wọ́n fẹ́ lọ́wọ́ ẹ̀mi àìrí tàbí láti bẹ̀bẹ̀ lórí ohun tí wọn kò fẹ́ tí ó ṣe é ṣe kí ó máa dí ìgbé-ayé ìrọ̀rùn wọn lọ́wọ́. Èrò àwọn olùsin Aláwòrò-Ẹkùn wọ̀nyí kín èrò Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2013:1-2) tí ó sọ pé:

> Ìwúre ni àwọn ìpèdè ìbùkún tó ń fi ìfẹ́ ọkàn awíre hàn sí agbàre. Àkànṣe àdúrà tí à ń pè ní ìwúre yìí jẹ́ ìlànà kan pàtó tí àwọn àgbà àtijọ́ fi máa ń bá àwọn òòṣà, òkú-ọ̀run pẹ̀lú àwọn alayé gbogbo sọ̀rọ̀ kí ire ó fi lè jẹ́ tọmọ ènìyàn kí àwùjọ wa ó lè tòrò. Ìwúre sì jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ètùtù àtigbàdegbà tí ó dá Yorùbá lójú, gẹ́gẹ́ bí òwèrè tí à ń jà, láti jẹ́ kí àyànmọ́ tàbí orírere ẹni ó leè kalẹ́.

Àkíyèsí wa ni pé ohun ti onímọ yìí sọ ni pé, ìwúre jẹ́ ìrúfẹ́ ètùtù kan, bẹ́ẹ̀ ni ó fi hàn pé ọ̀nà láti rawọ́ ẹ̀bẹ̀ àti láti wá ojú-rere òòṣà ni ìwúre. Ohun gbogbo tí onímọ̀ yìí tọ́ka pé ó lè mu ènìyàn wúre náà ni ó ṣokùnǹfà ìwúre ní ojúbọ Aláwòrò-Ẹkùn. Èyí fi hàn pé, èrò tó ń mú àwọn ènìyàn àwùjọ wúre kò fi bẹ́ẹ̀ yàtọ síra.

Ọ̀ṣùkù tó jẹ́ ọba Arárọ̀mí-Ale náà ni Abọrẹ̀ ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn, òun ló sì jẹ́ awúre àti adarí ètò gbogbo ni àkókò ìbọ. Díẹ̀ lára ìwúre tí ó wáyé ní ojúbọ nìwọ̀nyí:

| | |
|---|---|
| Ọ̀ṣùkù (Abọrẹ̀): | Tuuuu (ìṣe - títu ataare àti ẹmu sí ojúbọ) |
| Akópa: | Èèrì sẹ̀ |
| Ọ̀ṣùkù (Abọrẹ̀): | Yéèpaaa!! |
| | Tuuuu (ìṣe - títu ataare àti ẹmu sí ojúbọ) |
| Akópa: | Èèrì sẹ̀ ẹ̀ |

Òṣùkù (Abọrẹ̀): Yéèpaaa!!
Tuuuu (ìṣe - títu ataare àti ẹmu sí ojúbọ)
Akópa: Èèrì sẹ̀ ẹ̀ẹ̀ẹ̀
Òṣùkù (Abọrẹ̀): Yéèpaaa!!
Èní lọ́jọ́ ọ̀sẹ̀, èní lọjọ́ ìbọ
Èní lọjọ́ ìjẹ Aláwòrò tó tẹ Arárọ̀mí-Ale dó
Ọ̀sẹ̀ rere ni kó jẹ́ fún wa o
Akópa: Àṣẹ ẹẹ …

Ìwúre yìí ni Òṣùkù kọ́kọ́ ṣe kí ó tó bẹ̀rẹ̀ ètò gbogbo nípa ìbọ. Ní ààyè yìí, ó wúre fún ọmọ ilé Aláwòrò àti gbogbo àwọn akópa pàtápátá. Ẹmu àjáàbalẹ̀ tí wọn gbé kọ́ ère Aláwòrò-Ẹkùn lọ́rùn ní ojúbọ ni Òṣùkú bù sẹ́nu ni ó tu sí ojúbọ (tùùù) nígbà tí ó fẹ́ bẹ̀rẹ̀ ìwúre yìí. Òṣùkù (Abọrẹ̀) tún bu ataare tó pọ̀ níye sọ́wọ́, ó sì fi wúre báyìí;

Òṣùkù (Abọrẹ̀): Ata ni eléyìí oo,
Kíkún nilé ata máa ń kún
Ilé wa á kún fówó
Akópa: Àṣẹ!
Òṣùkù (Abọrẹ̀): Á kún fọ́mọ́
Akópa: Àṣẹ!
Òṣùkù (Abọrẹ̀): Àlàáfíà á jẹ́ tiwa
Akópa: Àṣẹ ẹẹ …
Òṣùkù (Abọrẹ̀): Kíkún ni ilé ataare máa ń kún,
Ilé yín a kún fún owó
Akópa: Àṣẹ!
Òṣùkù (Abọrẹ̀): Á kún fọ́mọ,
Akópa: Àṣẹ ẹẹ …
Òṣùkù (Abọrẹ̀): Obì ẹ rè é o Aláwòrò-Ẹkùn,
Obì a bikú danù fún wa o
Akópa: Àṣẹ ẹ
Òṣùkù (Abọrẹ̀): Á bi àrùn danù fún wa o
Akópa: Àṣẹ ẹ…
Òṣùkù (Abọrẹ̀): Gbéni gbéni kò ní gbé wa lọ́mọ́ o
Akópa: Àṣẹ! …
Òṣùkù (Abọrẹ̀): Nígbà tí wọ́n bá wá obì kiri tí wọ́n bá rí i,
wọ́n a ní ẹ pa obì,
Ayé ò ní wá wa pa o
Akópa: Àṣẹ ẹẹ
Òṣùkù (Abọrẹ̀): Ayé ò ní pa wá nípa kúpa
Akópa: Àṣẹ!...

Ó hàn nínú àyọlò òkè yìí pé, ataare, obì àti àwọn ohun èlò ìwúre mìíràn jẹ́ ohun pàtàkì nínú ìwúre. Èyí wà ní ìbámu pẹ̀lú èrò Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2013) tí ó ṣàlàyé nípa èro àwọn Yorùbá pé, 'bí ẹnu bá jẹ, ojú á tì' ní ọ̀rọ̀ ohun èlò jẹ́ nínú ìwúre àti pé ó jẹ́ àṣà Yorùbá láti máa tọjú ẹnu àwọn òòṣà wa kí a tó lè bèèrè ohunkóhun lọ́wọ́ wọn. Ìtọ́jú ẹnu ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn ni àwọn olùsin ń ṣe bí wọn ti lo àwọn ohun èlò ìwúre.

Ìrísí ohun èlò àti ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa wọn ni ó hàn nínú ìwúre àwọn olùsìn ní ojúbọ. Kíkún tí ilé ataare máa ń kún ni wọ́n fi wúre pé kí ohun rere kún ìgbésì-ayé ẹni tí wọ́n ń wúre fún. Àyọlò òkè yìí ń fi àjọṣepọ̀ tí ó wà láàrin obì, èrò ọ̀kan àwúre àti bí àwujọ̀ ṣe máa ń lo obì gẹ́gẹ́ bí àrokò ní àkókò ìwúre hàn. Èyí wà ní ìbámu pẹ̀lú èrò Pierce (1982: 35) tí ó sọ pé, "signs are not meaningful in isolation but only when they are interpreted in relation to each other in signifying system". (Àmì kò lé dá ìtumọ̀ ní, àyàfi tí a bá wò ó papọ̀ mó ohun tí ó jẹ mọ́). Èyí fi hàn pé, àjọṣepọ̀ tó ń wà láàrin àmì tí a lò àti ohun tí a fi rọ́pọ̀ ló jẹ́ kí a rí ìtumọ̀ ní kíkún gbé kàlẹ̀ nípa àmì àti iṣẹ́-ọnà tí a bá pàdé ní ojúbọ Aláwòrò-Ẹkùn. Irúfẹ́ àmì tí ó jẹ yọ yìí wà nínú àwọn àmì tí Saussure (1959) tọ́ka pé wọn jẹ́ 'alárokò' nítorí wọn kò fi nǹkan kan jọ ohun tí a fi wọ́n dúró fún.

Àmì pàtàkì ni ataare jẹ́ nínú ìwúre bí ó ti hàn nínú àyọlò òkè yìí. Ìrísí ohun èlò àti ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa wọn ni ó hàn nínú ìwúre àwọn olùsìn ní ojúbọ. Kíkún tí ilé ataare máa ń kún ni wọ́n fi wúre pé kí ohun rere kún ìgbésì-ayé ẹni tí wọ́n ń wúre fún. Bákan náà ni Ọ̀ṣùkù (abọrẹ̀) tún lo obì láti wúre bí ó ti máa ń wáyé níbi ìwúre ìbílẹ̀ láwùjọ Yorùbá. Kí ó tó fi obì yìí wúre, ó ṣàn án pẹ̀lú ẹmu àjáàbalẹ̀ sí ojúbọ. Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣáájú pé ẹmu àjáàbalẹ̀ jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú ohun èlò ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn, lára ohun tí àwọn olùsìn ń fi ẹmu àjáàbalẹ̀ ṣe ni ìwẹ̀nùmọ́, ohun náà ni wọ́n ṣe láàyè yìí. Ṣíṣe èyí ń fi hàn pé ohun mímọ ni wọ́n fi pàrokò ráńṣẹ́ sí ìbọ. Àyọlò òkè yìí ń fi àjọṣepọ̀ tí ó wà láàrin obì, èrò ọ̀kan àwúre àti bí àwujọ̀ ṣe máa ń lo obì ní àkókò ìwúre hàn. Àwọn ọ̀rọ̀ iṣe tí wọ́n lò mọ́ obì bí i 'wá', 'pa', àti 'bì' ní ó lò láti gbé gbólóhùn kalẹ̀ fún ìwúre. Ṣíṣe àṣàyàn ọ̀rọ̀ tútú láti wúre lójúbọ Aláwòrò-Ẹkùn wà ní ìbámu pẹ̀lú èrò Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2010: 26) tí ó sọ pé, "gbàlábọ ni èdè inú ìwúre", èyí tí ó túmọ̀ sí èdè tútù, èdè tí ó ń mú ìtùnú bá ọkàn ẹni, tí ó ń mú ọkàn ẹni balẹ̀. Ìlò àwọn ohun èlò ìwúre bí ó ti hàn nínú afọ̀ (ìwúre) òkè yìí wà ní ìbámu pẹ̀lú èrò Ajíbádé (2003: 25) tí ó tọ́ka pé, "àwọn ohun èlò kan wà tó jẹ́ pé wọn kò wà lásán, àti pé wọ́n ní ìtumọ̀ sí àwọn tó ń lò wọ́n…" Èrò onímọ̀ yìí ló hànde láàyè tí àwọn olùsìn ìbọ yìí lo ohun èlò bí i obi, orógbó, orógbó àti ataare láti fi hàn pé àjọṣepọ̀ wà láàrin afọ̀, olùsìn àti àwọn ohun èlò tí wọ́n múlò. A lẹ̀ sọ pé ohun èlò ojúbọ Aláwòrò-Ẹkùn kò dúró lásán nítorí àmì tí a lò àti ohun tí a fi rọ́pọ̀ (ire tí abọrẹ̀ wú fún àwọn akópa) ní àjọṣepọ̀ tó tẹ̀wọ̀n.



*Àwóran 5: Ìyálóde àti Abọrẹ̀ Aláwọ̀rọ̀-Ẹkùn ní Àkókò Ìwúrè*

## Èpè inú ìpohùn ìbọ Aláwọ̀rọ̀-Ẹkùn

Èpè ni Yorùbá ń lò láti sọ̀rọ̀ òdì tàbí pe aburú sayé èèyàn, ẹranko tàbí ohun aláìlẹ́mìí gbogbo tí wọ́n bá kórira tàbí tí ó bá ṣẹ̀. Èrò láti yaró ẹ̀ṣẹ̀ lára èèyàn tí a kò fẹ́ dáríjì ló ń ṣe okùnfà ṣíṣẹ́ èpè. Òté láti mú kí aburú ṣẹlẹ̀ sí irú èèyàn bẹ́ẹ̀ tàbí nǹkan kan ló máa ń mú kí Yorùbá ṣẹ́ èpè fún un. Èrò yìí wà ní ìbámu pẹ̀lú èrò Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2010: 26) tí ó tọ́ka pé ọ̀rọ̀ tàbí ohùn-òdì inú èpè jẹ́ gbàlákọ, èyí túmọ̀ sí ọ̀rọ̀ tí kò dára, tí ó dẹ́rù bani, èyí ni ó sì fà á tí àwọn ènìyàn fi bẹ̀rù èpè, tí yóò sì jẹ́ kí wọ́n jáwọ́ nínú iṣẹ́ ibi. Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2013:50) jẹ́ kí á mọ̀ pé iṣẹ́ méjì pàtàkì ni èpè- àkọ́kọ́ èrò tàbí ìṣẹ̀lẹ̀ inú èpè jẹ́ èrè fún ọ̀tá òǹgbùre nígbà tí èkejì jẹ́ ààbò fún òǹgbùre. Ọ̀kan-ò-jọ̀kan ìlò èpè lọ́nà tí onímọ̀ yìí àti àwọn mìíràn bẹ́ẹ̀ tọ́ka sí ni a bá pàdé ní ojúbọ ìbọ Aláwọ̀rọ̀-Ẹkùn.

Àwọn olùsìn Àláwọ̀rọ̀-Ẹkùn gbà pé, ẹ̀dá máa ń ní ọta àti pé ẹni tí a bá pè ní ọ̀tá kì í ro rere fún ẹ̀dá. Èyí ló mu wọ́n gbà pé àwọn lè lo ìpèdè òdì tí Yorùbá ń lò láti sọ ọ̀rọ̀ òdì sí aye irú ọ̀ta bẹ́ẹ̀. Bí Òṣùkú ti ń fi èpè ránṣẹ́ sí ọ̀tá àti èèyàn tí ó bá ro ibi sí ẹnikẹ́ni nínú àwọn tí ó wà ní ojúbọ àti gbogbo ọmọ Aláwọ̀rọ̀ lápapọ̀ náà ni àwọn olùsìn ń ṣe àṣẹ. Bí àpẹẹrẹ:

Àbọrẹ̀: Ọ̀tá ilé, ọ̀tá òde ni
Ọ̀tá ọkùnrin ni, ọ̀tá obìnrin ni
Ọmọdé ni, àgbà ni,
Tí ó ro aburú tàbí ṣe aburú síwa,
Aláwọ̀rọ̀ kó má pokùn so gbogbo wọn ni o

Akópa: Àṣẹ ẹẹ
Àbọrẹ̀: O máa ń pokùn so wọ́n ni
Èyí tó gbọ́, tó nóun ò ní gbà
Kí Aláwòrò-Àpónìkàn lọ pokùn so wọ́n kíákíá
Akópa: Àṣẹ!
Àbọrẹ̀: Agbára ẹ ṣì wà níbẹ̀, agbára ìgbà yẹn
Ó ní bí o ṣe ń ṣe é
Bí ẹnìkan bá ti ń bọ́mọ ẹ jà
Gbogbo ọ̀tá ilé, ọ̀tá òde,
Èyí táa mọ̀, èyí tí a kò mọ̀,
Aláwòrò-Àpónìkàn lọ bá wa pokùn so wọ́n
Akópa: Àṣẹ!

Yorùbá gbà pé, ọ̀tá wà nínú àwọn tí à jìjọ ń gbé ṣùgbọ́n tí wọn kò fojú hàn. Èyí ló mú kí wọ́n máa lo 'ẹnikẹni', 'gbogbo ẹni', ọkùnrin ni, obìnrin ni' 'ọ̀tá ilé' àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ bí ó ti hàn nínú àyọlò òkè yìí. Lílo àwọn ọ̀rọ̀ bí a tọ́ka sí wọ̀nyí fi hàn pé wọn kò mọ ẹni tí ó jẹ́ ọ̀tá àwọn, ṣùgbọn irú ọ̀rọ̀ báyìí tí kó gbogbo wọn pọ̀ láìdárúkọ wọn. Ìwádìí fi hàn pé, ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn máa ń ká gbogbo ọ̀tá olùfọkànsìn bí ẹni ká ẹja yíyan ni. 'Pokùnso' tí ó hàn nínú àyọlò yìí yàtọ̀ sí fifi okùn síso okun mọ́ nǹkan gíga tàbí ìgi láti fi bọrun gba ẹ́mi ara ẹni. 'Pokùnso inú àyọlò òkè yìí túmọ̀ sí pé ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn yóò dìídì fi okùn so ẹni tí a gbé ṣepe tàbi ọ̀tá ní ìkákò bí ẹja tí wọn fẹ́ yan lórí iná. Èpè mìíràn tí à rí ní ojúbọ yìí hàn nínú ìwúre báyìí:

Abọrẹ̀: Ọ̀tà tó bá lóun fẹ́ ṣe àwa,
Ìdùbúlẹ̀ ni ajá ti ń fún ọmọ rẹ̀ lóúnjẹ
Ìdùbúlẹ̀ ni ẹlẹ́dẹ̀ ti ń fọ́mọ ẹ̀ lóúnjẹ
Ìdùbúlẹ̀ ni wọn yóò ti máa fún wọn lóúnjẹ
Akópà: Àṣẹ!
Abọrẹ̀: Ìdùbúlẹ̀ ni ẹlẹ́dẹ̀ ti ń fọ́mọ ẹ̀ lọ́mú,
Gbogbo ọ̀tá wa pátápátá,
Ìdùbúlẹ̀ ni wọn ma máa wà
Akópà: Àṣẹ!

Ìrísí ajá àti ẹlẹ́dẹ̀ nígbà tí àwọn ọmọ wọn bá ń mu ọmú ni abọrẹ̀ wò pé kí àwọn ọ̀tá àwọn náà máa wà nígbà gbogbo. Àmì tí ó hàn nínú àyọlò yìí wà ní ìbámu pẹ̀lú àwọn àmi tí Eagleton (1988: 101) pé ní àmì onítọ̀ọ́ka tí ó jẹ́ pé nǹkan díẹ̀ ló ní í ṣe pẹ̀lú ohun tó dúró fún. Àrokò tí wọ́n pa pẹ̀lú èyí ni pé, kí àwọn ọ̀tá wà ní ìdùbúlẹ̀ àárẹ̀ ní gbogbo ayé wọn. Ìwádìí fi hàn pé, bí èrò wọn bá fi ṣẹ mọ́ ọ̀tá lára, kò ní ráyé lépa àwọn mọ́, àwọn àti ẹbí àwọn yóò sì máa gbáyé ṣe ohun rere. Ìmọ̀ nípa àṣà àti èdè àwùjọ tó ni ìpohùn yìí ló hú ìtumọ̀

tí ó jinlẹ̀ nípa ewì yìí jáde. Kókó-ọ̀rọ̀ yìí wà ní ìbámu pẹ̀lú èrò Davy (1999) ọkan lára àwọn agbátẹrù tíọ̀rì ìfiwádìí-sọ̀tumọ̀ tí ó gbà pé, lámèétọ́ kò gbọdọ̀ ta kété sí èdè inú afọ̀, bí bẹ́ẹ̀ kọ́ yóò nira fún un láti fún afọ̀ ní ìtumọ̀ yéké yéké.

## Ọfọ̀ inú Ìpohùn Aláwòrò-Ẹkùn

Ọkan pàtàkì nínú àrángbọ́ tí ó jẹ́ ewì àwíṣẹ Yorùbá ni ọfọ̀. Àwọn onímọ̀ kan gbà pé, ọfọ̀ àti ògèdè súnmọ́ ara wọn, ó sì ṣòro láti tọ́ka sí ìyàtọ̀ wọn. Fọlọ́runṣọ́ (1982: 13) ṣàlàyé pé, "ọfọ̀ náà ni Yorùbá ń pè ní ògèdè". Èrò onímọ̀ yìí ni pé, ewì alohùn tí Yorùbá ń pè ní ògèdè náà ni wọ́n ń pè ní ọfọ̀, èyí fi hàn pé, ewì alohùn kan tó ní orúkọ méjì ni ọfọ̀ jẹ́.

Àwọn Yorùbá a máa pe ọfọ̀ ní àkókò ìwúre, èpè tàbí nínú àwọn ewì alohùn wọn mìíràn gbogbo. Yorùbá a máa lo ọfọ̀ nígbà ìṣòro yálà fún rere tàbí fún ibi. A rí àgbékalẹ̀ ọfọ̀ ní ojúbọ Aláwòrò-Ẹkùn. Ọ̀pọ̀ nínú àwọn ìsọ̀rí ewì alohùn Yorùbá ló fààyè gba ìlò ọfọ̀, bẹ́ẹ̀ kì í ṣe ohun èèwọ̀ ní ojúbọ Aláwòrò-Ẹkùn. A rí ìlò ọfọ̀ láàrin ìwúre ní ojúbọ Aláwòrò-Ẹkùn. Nígbà tí Ọ̀ṣùkù-Alále (abọrẹ̀) ń wúre pẹ̀lú ataare báyìí:

| | |
|---|---|
| Ọ̀ṣùkù (Abọrẹ̀): | Bí ọkùnrin bá jata, á tá a lẹ́nu, |
| | Bí obìnrin bá jẹ ẹ́, á tá a lẹ́nu, |
| | Bí ọmọdé bá jẹ ẹ́, á tá a lẹ́nu, |
| | Bí àgbà bá jẹ ẹ́, á ta á lẹ́nu, |
| | Bí ata bá kan èèyàn lára, á ta á |
| Akópa: | Bẹ́ẹ̀ ni… |
| Ọ̀ṣùkù (Abọrẹ̀): | Kí ọ̀rọ̀ wa kó lè ta á lára, kí ó tètè ṣe é kíákíá |
| Akópa: | Àṣẹ! |
| Ọ̀ṣùkù (Abọrẹ̀): | Kí ẹ rọ̀jò ìrànlọ́wọ́ fún wa |
| Akópa: | Àṣẹ ẹẹ… |

Ìpèdè àwíṣẹ ni ọfọ̀ jẹ́, ìwádìí fi hàn pé kò sí ohun tí Yorùbá kò lè pè ọfọ̀ sí. Àwọn ọ̀rọ̀ tí a falà sí nídìí nínú àyọlò òkè yìí jẹ́ gbólóhùn bítií-rí àti máyẹ tí Yorùbá gbà pé ó lè mú kí èrò wọn wá sí ìmúṣẹ nínú ọfọ̀. Ó hàn nínú àyọlò òkè yìí pé Ọ̀ṣùkù (Abọrẹ̀) ń fẹ́ kí ohun tí ó ń bèèrè lọ́wọ́ ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn wá sí ìmúṣẹ ni ó ṣe pe ọfọ̀ àwíṣẹ yìí pẹ̀lú ataare. Títa ataare nígbà gbogbo àti lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ ni ó lò láti fi sọ bí wọn ṣe ń fẹ́ kí ọ̀rọ̀ wọn ká (ta) ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn lára kí ó sì ṣe é ohun tí wọ́n fẹ ní kíákíá.

## Oríkì inú Ìpohùn ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn

Oríkì ni àkójọpọ̀ ọ̀rọ̀ ìwúrí àti ọ̀rọ̀ atunilára tí a gbé kalẹ̀ nípa ìran kan, ìdílé kàn tàbí èèyàn kan ní pàtó, bẹ́ẹ̀ ni ó sì lè jẹ́ nípa ìbọ. Iṣẹ́, ìṣe, ìhùwàsí, ìrísí, àbùkù, èèwọ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ nípa ìran tàbí ẹni tí a ń kì máa ń jẹ yọ nínú oríkì tí a hunpọ̀ fún un. Oríkì lè jẹ́ ọlọ́pọ̀ ọ̀rọ̀ tàbí ẹyọ ọ̀rọ̀. Lọ́pọ̀ ìgbà a máa

ń bá oríkì nínú àwọn ìsọ̀rí lítíréṣọ̀ alohùn yókù. Iṣẹ́ ìwúrí àti mímú kí inú ẹni dùn ní oríkì máa ń ṣe fún èèyàn, ẹ̀mí àìrí tàbí ìbọ tí a gbé e kalẹ̀ fún. Ìwádìí fi múlẹ̀ pé, bí Yorùbá ti ní oríkì fún àwọn èèyàn náà ni wọ́n ní fún àwọn ìbọ tí wọ́n ń sin àti àwọn ohun èlò ìbọ̀, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n sì tún ń ṣe àmúlò oríkì nínú bíbọ Aláwòrò-Ẹkùn.

Nínú ìbọ yìí, bí a ti rí àfihàn oríkì ìbọ yìí, ni a rí oríkì àwọn ìran tí ó gbé ìbọ yìí dé ààyè tí ó wà lónìí, bẹ́ẹ̀ ni a sì tún rí oríkì àdájẹ́ ìbọ yìí. Àpẹẹrẹ oríkì àwọn olùsin ìbọ yìí:

Àwọn Olùsìn: Ọmọba Aléjùgbè bí ìta
Ọmọ Oshuku Iyonbu Aléjùgbè
Ọmọ ọba Akokolejugbe.
Ọmọ Aláwòrò Ẹkùn tí ń ṣọdẹ fìrù gbálẹ̀
Ọmọ ogbè, ọmọ ọta,
Ọmọ òkúnnù òpópó lẹja
Ọmọ Alekoko-bí-ọṣán (òwú)
Ọmọ A-ti-ṣaṣara-bomi
Ọmọ mámu mámu tèmi nìkan kọ́,
Tẹbí mi ni.
Ọmọ Ifẹ̀-Oòyè níbi ojúmọ ti ń mọ́ wálé ayé
Yéèpàà yéèpààà…

Ìwádìí fi hàn pé, àkókò tí orin tàbí ètò ìbọ bá wọra ni àwọn olùsìn máa ń ki ara wọn pẹ̀lú oríkì yìí láti fi hàn pé ọmọ ọkọ àti ojúlówó olùfọkànsìn tòótọ́ ni àwọn. Àwọn baba ńlá ìdílé tí ó mú ìbọ yìí wọ̀lú ni Aléjùgbè àti Ọ̀ṣùkù Iyonbu. Ìṣe wọn gẹ́gẹ́ bí èèyàn lílé ló hàn nínú oríkì yìí nígbà tí wọ́n kì wọ́n ní "Alekoko-bí-ọṣán" àti "ọmọ ọta". Àfihàn ìran yìí gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó ṣe é fọkàn tán jẹ yọ láàyè tí awọ́n olùsìn ti ki ara wọ́n ní, "Ọmọ mámu mámu tèmi nìkan kọ́, tebí mi ni". Èyí fi hàn pé, ohunkóhun tí èèyàn bá fi ṣọ àwọn olùsìn ìbọ yìí máa rí ìdáàbòbò tó péye. Ọ̀ṣùkù (abọrẹ̀) ìbọ yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé, irú ìṣe àti ìwá yìí jẹ́ dandan fún gbogbo olùfọkànsìn ìbọ yìí. Oríkì míìràn tí a tún rí ní ojúbọ Aláwòrò-Ẹkùn ni oríkì orúkọ tàbí ìnagijẹ ìbọ yìí tí ó jẹ yọ nígbà tí àwọn olùsìn ń kọrin báyìí:

Àjọkọ: Ó ti mí gbọ́ gbogbo lẹ̀ mí sọ o
Ó gbọ́ gbọ ọ, ọọmọlẹ̀ aawo
Aláwòrò gbọ́ gbogbo à mí fọ ọọ
Ó gbọ́ gbọ ọ, ọọmọlẹ̀ aawo
<u>Ọta</u> mi gbọ́ gbogbo lẹ̀ sọ ọ o
Ó gbọ́ gbọ ọ, ọọmọlẹ̀ aawo

Aláwòrò-Ẹkùn ni wọ́n tọ́ka sí gẹ́gẹ́ "Ọta" nínú orin òkè yìí, wọ́n sì fi hàn pé ó ti gbọ́, ó sì ti gba gbogbo ètùtù tí àwọn ṣe. Oríkì ìnagijẹ mìíràn tún fara hàn nígbà tí Òṣùkù ń wúrè nídìí ìbọ báyìí:

Òṣùkù (Abọrẹ̀): Àwọn èèyàn wa tí wọ́n mú owó tí wọ́n ná,
Aláwòrò Agbónìkàn fi ọ̀pọ̀ rọ́pò fún wọn o
Akópa: Àṣẹ ẹ
Òṣùkù (Abọrẹ̀): Èyí tí a fẹ́ Aláwòrò Agbónìkàn a jẹ́ kó ṣẹ mọ́ ẹ lára o
Akópa: Àṣẹ ẹ

"Agbónìkàn" tí a falà sí nídìí nínú àyọlò òkè yìí jẹ́ oríkì ìnagijẹ ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn. Ìwádìí fi hàn pé, oríkì yìí máa ń jẹ́ ohun ìwúrí fún ìbọ, èyí ló mú àwọn kí Òṣùkù máa fi sí ààrín ìwúre kí inú Aláwòrò lè dùn láti ṣe ohun tí wọ́n ń tọrọ lọ́wọ́ rẹ̀ ní kíákíá. Èyí kò jẹ́ ìyàlẹ́nu nítorí lára ohun tí Yorùbá ń lo oríkì fún ni mímú ìwúrí bá ẹni tí a kì.

## Agbálọgbábọ

Ó hàn gbangba pé, ipò pàtàkì ni ewì alohùn ń kó nínú bíbọ ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn abo láàrin Àwórì ní ìpínlẹ̀ Èkó. Àmúlò ọ̀kan-ò-jọ̀kan ewì alohùn Yorùbá ní ojúbọ àti ní àkokò ayẹyẹ ìbọ jẹ́ ohun pàtàkì, lára àwọn ewì alohun tí a bá pàdé ni ojúbọ yìí ni ìwúre, èpè, ọfọ̀ àti oríkì. Ó hàn gbangba pé, ìwúre gan-an ló jẹ́ olúborí, a rí ìwúre nínú orin tí àwọn olùsìn kọ́, bẹ́ẹ̀ ni a rí ìwúre tí wọ́n gbé kalẹ̀ pẹ̀lú ohun ìsàré àti àrángbọ́/ìsọ̀rọ̀kéwì. Ní kété lẹ́yìn ìjúbà ìwúre ló tẹ̀le ní ojúbọ. Ọ̀kan-ò-jọ̀kan ohun èlò ìwúre tí Yorùbá máa ń múlò bí i obì, orógbó àti ataare ní abọrẹ̀ lò láti wúre ní ojúbọ. Iṣẹ́-ọnà, ohun èlò ìwúre àti ewì alohùn lọ́kan-ò-jọ̀kan tí a bá pàdé ní ojúbọ ìbọ Aláwòrò-Ẹkùn ní ó ń fi hàn pé, wọ́n ní ìtumọ̀ ìjìnlẹ̀ sí àwọn ìbọ. Bẹ́ẹ̀ ni ó sì hàn pé, àjọṣọ àti ajọmọ̀ wà láàrin àwọn olùsìn, àbọrẹ̀, ẹ̀mí àìrí àti Aláwòrò-Ẹkùn. Bẹ́ẹ̀ ni ó hàn pé takọ-tabo ló ni ipa tí wọ́n ń kó nínú bíbọ ìbọ àti ṣìṣe ayẹyẹ ní ojúbọ Aláwòrò-Ẹkùn.

## Ìwé Ìtọ́kasí

Adeyeri, J.O (2012). Socio-Economic Significance of Cultural Festivals in Epe Division of Lagos State: An Overview in *International Journal of Research in Arts and Social Sciences.* Vol 4

Agbabiaka, H.I (2016). Physical planning implication of Eyo festival in Lagos Island, Nigeria in an online *Journal of Cogent Social Sciences.* https://doi.org/10.

Ajíbádé, G. O. (2003). "Àgbéyẹ̀wò Awo Ọ̀ṣun àti Àwùjọ Òṣogbo nínú Iṣẹ́-ọnà Ajẹméwì àti Ajẹmáwòrán". Ilé-Ifẹ̀, Ph.D. Thesis, Ọbáfẹ́mi Awolọ́wọ̀ University.

Chafetz, J.S (1999). *Handbook of the Sociology of Gender.* New York: Kluwer Academic/Plenum Print.

Davy E.K (1999). *Hermeneutical Inquiry: The Interpretation of Texts.* United State, Westminster John Knox Press.

Eagleton, T. (1983). *Literary Theory: An Introduction.* London, T.J. Press.

Fọlọ́runṣọ́ (1998). *The Written Yorùbá Poetry (1949-1989), A Study in Sociology of Literature.* (Ph. D Thesis). Ìbàdàn, University of Ìbàdàn.

Gadamer, H. (1977): *Philosophical Hremeneutics Translated by David E.* Linge, Berkeley. University of Califonia Press

Heidegger, M. (1962). *On the Way to Language.* New York, Harper and Row.

Husserl, E. (1964). *The Idea of Phenomenology.* Translated by William P. Alston and George Nakhnikian, Martinus Nijhoff, The Hague.

Ìdòwú-Ọ̀shọ́, O. (2005). "The Ẹ̀rùngbè Traditional Oral Poetry in Ìkòròdú, Southwestern Nigeria". Ìbàdàn, Ph.D. Thesis, University of Ìbàdàn.

Iser, W. (1980). "Interview" DIACRITICS: A Review of Contemporary Criticism, Summer, vol 28. No.6.

Johnson, S. (1921). *The History of the Yorùbás.* London: CMS Bookshop.

Killermann (2017: 3). *A guide to Gender: The Social Justice Advocates Handbook*. New York: Impetus Books.

Loko, O. O (2014). Song Texts, Theme and Roles of Vocal Music in Egungun Traditional Festival in Akesan, Awori land of Lagos State in *Mediterranean Journal of Social Sciences*. Rome-Italy, MCSER Publishing. Vol 5 No 7.

Obasola K. E. (2014). Religious Tourism and Sustainable Development: A Study of Eyo Festival in Lagos, Nigeria in *an International J. Social Science & Education*. Vol.4 2227-393X Print 524

Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2010), A. (2010). *Ìtúpalẹ̀ Èpè.* Ilé-Ifẹ̀: Ọbáfẹmi Awolọwọ University Press.

Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2013), A. (2013). *Ìtúpalẹ̀ Ìwúre*. Ìbàdàn. DALAG Prints and Park.

Pierce, C.S (1982). *Body as a Medium of Expression.* Cambridge: Harvard University Press.

Saussure, Ferdinand (1959). *Course in General Linguistics*. New York: Philosophical Library.

Simone de Beauvoir (1973). *The Second Sex*. New York: Vintage Books.

Vidal T. (2015). "The Role and Function of Music at Yoruba Festivals. African Musicology: Current Trends." In *Discourse in African Musicology: J.H. Kwabena Nketia Festschrift*, eds. Kwasi Ampene, Akosua Adomako Ampofo, Godwin K. Adjei, and Albert K. Awedoba, Ann Arbor: Michigan Publishing Services, 56-64.